# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 128. SATURDAY, DEC. 27, 1924. Fourpence.

**Circulation 1,200 Copies Weekly.**



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods*

"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails, Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹke Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruká, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa: A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ Agbado, I[illegible], Ọti Eleworo (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn [illegible] Aṣọ Iyọṣọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipon abẹ oni *Diamond* [illegible] (*Italy*). [illegible] Gold Coast, Accra, Lome [illegible]

## Keresimesi Baba Arugbo-k[e]
## keje yio se bebe ni Sabu
## awon Oyinbo

## *OLOWO S'OKE DI'LE*

l'ojo die si i.

E wa wo bira re.

---

# OLD DADDY XMAS
## WILL ARRIVE AT
# LEVER STORES
## IN A FEW DAYS.
## COME AND SEE HIM.

abi lati fi han pe iku ko so fun ẹnikan igba tabi akoko ti yio de ba ẹnikẹni? Ninu ọrọ ọkunrin na o mu mi ranti owe awa ọmọ Yoruba kan ti o wipe; Ori ko mọ ibusun iba ti tun ilẹ ibẹ ṣe, iku ma npa olore; Ẹnyin iya ati baba 'mi, nipa ti Oluwa awọn ti nwọn ni ero pe, awọn nṣe ogo ninu wọn ti ohun alumọni aiye yi si wa ni ikawọ wọn ti nwọn ko mọ wipe a fi si itọju wọn ni, nipa bẹ lati le ma fẹju mọ wa mọ ni igboya lati sọ fun ẹnyin mẹkunnu ẹlẹgbẹ mi abi alai mọ iwe ka bi emi nihin wipe kosi ofin Igẹsi kan ti o ni ọwọ ninu ile Isin Ọlọrun wa, o eyiti o ni agbara pupọ ninu ofin Igẹsi ni eyi ti awọn aṣofin npe ni *Criminal-Codes* iyẹn, ko kan wa ni Ṣọṣi wa o.

Boya awọn ọmọwe ijọ ti nwọn bẹrẹ si bu ni ọjọ ọsẹ ti nwọn sọ fun wa pe ki a lọ si ile'we ẹkẹji ti nwọn si ni ki a lọ ra iwe eyiti agba kan wi fun wa eyiti o pe ni elo abi ilanọ ti ẹsin ti *Ebenezer* abi ti *Baptist Churches* ki o jọwọ juwe fun wa nibo ni a le ri iwe na ra, abi ni ile ita iwe ti Revd. David ni? Nitori awa mọ wipe ara *America* ni alagba na awọn ẹniti nwọn mọ itan ati orile ologbe David ti o mu Isin eyiti a tun pada tun yi si ọna omiran yi.

Mo sọ eyi fun itiju nyin ati fun itan awọn iran ti wọn o tun dide boya lẹhin emi na.

KADUNA STORES.

---

## IKU IMAM ADAM—BABA ADINI EKO.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Bi iku ba gba owo, Rabi alaṣọ le san, bi iku ba gba ẹbẹ, gbogbo janma le b ẹ ẹ, ṣugbọn a bẹ bẹ'ku bẹ'ku, iku ko gbọ, iku gba Baba Adini lọwọ wa. Ko si ẹbọ tabi ogun aiku, Oyinbo ko le ṣe e, ara Ibariba kò le ṣe e, Baba... a ku, oniṣegun a r'ọrun, adahuṣe ko ni gbe ...ẹ.

Imam tabi Lemọmu Adamọ to ku lojọ Satide ọsẹ to kọja, *January 19th*, ti a si sin nijọ keji ni Baba Adini kẹfa to jẹ l' Eko larin Imale. Ẹniti a ranti pe o kọkọ jẹ oye na ni Alufa Arumọni ni nwọn ọdun mẹtalelogorin sẹhin, lẹhin na Shitta Bey, lẹhin na Yesufu Shitta Bey, lẹhin, na Apatira ti ita Faji, ko to wa kan Baṣọrun Tiamiyu Savage ipo ẹniti ologbe ti a nsọrọ rẹ yi rọ ni iwọn ọdun marun sẹhin, *July 1st 1919.*

Afinju ati arẹwa enia ni Baba Adini nṣe. Awọn Papai Aguda ni o tọ ọ lati kekere; iṣẹ ti o si mọ daradara ni iṣẹ aranṣọ ti oyinbo npe ni "*Tailor.*" *Tailor* ti Baba Adini ko nṣe ti buba, agbada tabi ṣokoto abẹdan, bikoṣe ti oyinbo, ọgọrọ ninu awọn Papai Aguda igbani ni o si da ẹwu bi *Frock Coat* ati ṣokoto "*London bag*" fun. Lẹhin ti o fi aṣọ riran silẹ, o bẹrẹ si kọ kewu lọdọ Alufa Abu, ọgọta Izbu tabi Esu ti awọn ọmọde miran nfi ọdun mẹrin kọ ni isisiyi, ko gba Baba Adini ju ọdun kan pẹlu abọ lọ, ki o to ke gbogbo rẹ jakejado to si bẹrẹsi ke Ilmu tabi Ilimi, tobẹ ti awọn ẹgbẹ rẹ nigbana fi nwipe Anjọnu lo nko ni kewu loru.

Lakoko yi lo fẹ Barikisu ologbe iyale rẹ, akọbi awọn mejeji si ni Lawani ẹniti o ku nigbati o nke ogun Esu lọwọ. Lẹhin eyi o lọ si Abẹokuta, aya rẹ keji si ni Asana nigbati o pada de lati Abẹokuta, ni ọrẹ rẹ kan-ẹniti awọn mejeji jọ kọ kewu pọ lọdọ Alufa Abu fi Samọta ọmọ rẹ ta lọrẹ, nigbana ni Baba Adini ṣẹṣẹ wa ṣe Wolima ko to gbe Samọta iya Rabi Alaṣọ n' iyawo. Lati igba yi lọ ni asiki ti ngori asiki fun awọn mejeji titi Samọta fi gbe pẹtẹsi nla duro, awoyirun.

Nigbati Abudu Kadiri ẹniti o kọkọ jẹ Lemọmu si Moṣalaṣi ti a npe ni Alfayat Mosque nisisiyi ku, Adamọ—Baba Adini lo rọ po rẹ, o si ṣe iṣẹ pupọ nibẹ titi ogbo fi de, ti nwọn si fi Alufa Sumọnu ẹniti ao fi jẹ Lemọmu dipo rẹ, ṣe aṣoju rẹ nigbana.

Baba Adini ko fi ọran ẹsin ṣire, o si wa ni Moṣalaṣi Jimọ nijọ ti awọn panapana ṣe ohun ewọ, ti nwọn si tu omi le awọn Janma lori. Baba totọ ni Baba Adini ologbe nṣe, ọfọ nla ni iku rẹ jẹ fun Imale Eko, opo nla lo si yẹ n'ilu ati l'adugbo rẹ pẹlu. O ṣe! ẹni rere lọ K'Ọlọrun fi ọrun kẹ, ko si tọju gbogbo ile ati ọna rẹ—pata'i awọn Fatumọ, Rabiatu Iyalode, Nọfisatu, Sabitiyu ati Yaya ọmọ rẹ.

A dupẹ lọwọ gbogbo Musulumi to lọ sibi oku Baba Adini, a si tun dupẹ lọwọ awọn Kiriyo bi Lọya E. J. Alex Taylor, Ọgbẹni Phillip Williams ati awọn jakan-jankan miran pẹlu. Seriki, Mọgaji, Adewale, Saka Muyẹ, a ki gbogbo nyin kabọ ẹ ku irin ọjọ

Ki ilu maṣe jafara ati yan ẹlomiran si ipo ologbe; a si tan ma pe bi a ba ti yan ẹnikan pataki to tọ si, iba ṣe Alufa to ti ni ilẹ ti a kọ Moṣalaṣi oke arin si, a ki yio ri ẹniti awọn kan tun ma fi jẹ oye elekuru. E maṣe da awọn to ni ki ẹ fi emi Atari Ajanaku jẹ oye Baba Adini lọhun o, wọn ko fẹ ki nkowe sinu "Eko Akete" mọ ni, ki awọn ọbaiyejẹ le r'aye lati ma ṣe gegele l'ori gegele, bẹni emi pelu wọn di-ka-re-wa.

Rabi ọmọ oloku, ẹ ku inawo, ẹ ku aṣẹhinde ọmọ a ṣe bẹ fun ẹnyin na.

OMODE NBU IROKO, O NB'OJU WO EHIN.

Ninu iwe irohin *African Messenger* ti *Thursday, January 17th 1924*, isọkusọ wo lo ku ti ọmọde oniwe irohin na ko so tan si Loya Shyngle ati Ọgbẹni Macauley lara, nipa ọrọ Imale, ọrọ Eleko, ọrọ ofin ilu, ati ọrọ owo s'san (*taxes*).

*Civilization*, tabi ilaju Oyinbo, yio ma da nkan silẹ, bikoṣe iyẹn nkọ? nibo ni Oniwe irohin *African Messenger* ti ja wa, ti ko l'okun lọrun to ma wipe awọn agbalagba ati enia pataki n'lu to ti bi ọmọ to firi on papa bi ẹgba firi okan ni on ma fi kọ oju fin. Igi ma da o! Ibaṣepe Loya Shyngle ati Ọgbẹni Macaulay fẹ lati Kọngọ fun iwe irohin *African Messenger* fun isọkusọ rẹ, oniwe irohin na iba ti so agbeje mọ idi; ṣugbọn loju mi, o dabi ẹnipe awọn mejeji ka ọrọ rẹ si ọrọ alafebipa ti ko to yẹsi. Otitọ ni oyinbo np'owe pe "*Fools rush in where Angels fear to tread.*"

Emi ni ti nyin nitotọ
ATARI AJANAKU.

---

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, JANUARY 26, 1924.

---

### IBADAN ỌMỌ AJORO SUN, ỌMỌ AFIKARAWUN FỌ'RI MU!

A ko le ṣalai ba awọn ara Ibadan yọ fun Iwe-irohin kan ti Ọgbẹni D. A. Ọbasa ṣẹṣẹ bẹrẹ si ṣe larin nwọn, lara eyiti o fi ẹdà rẹ kan ṣọwọ si wa ni lọbọyi. *Yoruba News* (Iwe-irohin ti Yoruba) ni orukọ ti o sọ iwe na gẹgẹ bi a ti wi nişiwaju; surà rẹ si jọ Iwe-irohin tiwa—*Eko Akete.* Igbagbọ wa ni pe ọran iyan ni fun ilu ti o ba nla kaka ninu Ilaju ati Ẹkọ lati ni Iwe-irohin tirẹ, ati pe irufẹ Ilu ti o ba nlaju ti ko ba si ni Iwe-irohin kan si wa ni ipo ẹhin patapata; nitoripe Iwe-irohin dabi jigi fun awọn ẹlomiran to wa ni okere lati ma fi wo bi ilu kan ti nlọsiwaju si; o si ni iṣẹ pupọ ti o nṣe larin awọn enia fun rere wọn ati fun titọkasi ohun alebu ti o le wa ni Ilu na.

Ni ọjọ Jọjọ (o to iwọn ọdun 1904) ni Ijọba Alake ni Abẹokuta ti ni Iwe-irohin kan ti a npe ni Iwe-irohin Ijoba Ẹgba (*Egba Government Gazette*) ni igba aiye Ọba Gbadebọ afun ka'ko bi agbọn, atẹ'di alaṣeju bo'mi gbigbona eyiti o ṣe iṣẹ rere lọpọlọpọ ni sa tirẹ; ṣugbọn anu ṣe ni pe lati igbati ati mu u ki o kogba sile, kosi Iwe-irohin miran ni Ilu na mọ. Lọju wa, eyi jẹ ohun alebu pupọ pe bi Abẹokuta ti ni Ẹkọ ati Imọ tõ ni, a ko le fi Ogún Iwe-irohin kan gba'ri nibẹ.

A tanma pe irufẹ ipa ti Ọgbẹni Ọbasa nsa nisinsinyi ni Ibadan, lati ma ṣe Iwe-irohin nibẹ—eyiti didasilẹ rẹ ti jẹ ọran ẹdun fun diẹ ninu awọn ọrẹ ti a mọ nibẹ ni iwọn ọdun mejọ sẹhin—yio jẹ iṣiri fun awọn Ilu pataki-pataki miran lagbegbe Eko lati tẹ atẹsiwaju lọna yi.

A kan sara si Ọgbẹni C. Labour to ṣe fitafita diẹ lati ma ṣe Iwe-irohin ti a npe ni "*The Aurora*" eyini ni "Imọlẹ Owurọ," ni *Onitsha*, ati lẹhinna ni *Calabar*, ni igbakan.

Iwe-irohin ki iṣe ọta ẹnikẹni ni ilu, awọn ẹniti iṣẹ wọn buru, ti nwọn si korira imọlẹ,—gẹgẹbi ọrọ Kristi—lo le ma ṣe kọkọa si Iwe-irohin.

A ba gbogbo awọn ara wa ni igboro Ibadan yọ. A ba Ajẹlẹ Pataki yọ (Hon. Capt. Ross C.M.G.) A ba Ṣitu Baiẹ yọ, a ba Balogun Ṣowẹnmọ yọ, a ba Salami Agbaje yọ, a ba Alufa Okuṣẹhinde yọ, a ba Alagba E. H. Oke yọ, ati awọn Isọri-isọri miran, fun Imọlẹ ti a tan larin wọn yi, a si tanma pe ninu õfi ọlã ti oju Oniwe Irohin nri, nwọn ki yio fa iranlọwọ nwọn sẹhin fun Ọgbẹni Oniwe Irohin yi.

Iwaju, iwaju, ni ki ọpa ẹbiti rẹ ma re si! O ku, *Yoruba News*, Ọrun Ibikunle Oloke, Ọrun Ogunmọla olodogbo-kẹ̀rílógún, Ọrun Ajayi o gbori-ẹfọn-sa-filafila, a gbe o, iwọ ọmọ Oke Ibadan, ma wo'lẹ, a lẹhin maṣe'mẹlẹ!!!

---

THANKS FOR SYMPATHY.

Mr. Wahabi M. Anjorin and family, beg to thank all friends and acquaintances who have, by letters and personal calls, sympathised with them in the loss they have recently sustained by the death of their beloved father, Momodu Anjorin who departed this life on Wednesday 10th Jan, 1924.

WAHABI M. ANJORIN.

## FACTS AND FIGURES

### THE DECLINE OF A ONCE POPULAR JOURNAL.

**"The Times of Nigeria" And Its Editorial Chair.**

The reference made in the columns of a local contemporary has made us enquire for some copies of recent issues of *The Times of Nigeria* which, by the way, we were not aware has started coming out again.

Ill got up and ill-printed, this once popular journal excited a good deal of sympathy as one goes through its rough pages swelled up with grammatical irregularities and not bearing the appearance of being ever proof-read even from the printer's galley. With still more sympathy one looks back at the days of its glory when it stood out as a premier paper for Nigeria. Those were the days of the late Mr. Bright Davies, its founder, who sat in its editorial sanctum for a considerable length of time.

When it was transfered in the year 1919 to the Jamat Party, far-seeing people had almost then foreseen the decline into which the paper has now fallen.

After the death of Mr. Bright Davies, Messrs Walter L. Edwin and B. Ade. Mumuney took up the roles of Editor and Assistant Editor respectively.

The paper then tried to show up—with men like Professor Adeoye Deniga, Patriarch J. G. Campbell and others contributing to its columns—but with a marked change and only for a time, for the whole scene changed again and both the Editor and his Assistant left the office in succession. The present decline then actually dawned upon the paper and its Editorial chair began to be unstable. Messrs P. Peters B.A., and L. J. Buckle came on the scene (one after the other) and left.

For sometime the paper went on without an Editor known to the public.

The proprietor Mr. Adam I. Animashaun, who is generally known at present as its Editor, does not posses the necessary qualification, educationally, that makes up an Editor, or, at least, a good one and we may humbly advise him either to engage competent hands or close up the business in the interest of good taste.

The paper, as it is now, does not reflect credit on the Lagos community. There is a philosophy in the saying that :—

Whatever is worth doing, is worth doing WELL.

ADEKANBI.

### *STOP PRESS!!!*

**Record-breaking Fair!**

We have been favoured with a dossier of leaflets explanatory of The Vienna Fair (Venice) fixed for March 9—15 next, which bids fair to be one of the wonders of the present year.

Particulars can be had at Messrs A. Kessler of 7, Labinjo Lane, Lagos.

**National Congress.**

Several friends in town were recently communicated with, by Mr. Samuel Richard Wood, Secretary of the above Congress, regarding the proposed visit to Nigeria, of some of the leading members of the body from Sierra Leone and the Gold Coast, in order to investigate the cause of the amazing indifference of the *Personnel* of the local Branch.


# John Holt & Co.,

## ( Liverpool ) Ltd.

"Flag" Cigarettes

"Elephant" Cycles

Rudge-Whitworth Cycles

Crockery

Enamelware

Dried Fish

Flour

Sulphur

White Lime

Alum

Coal Tar

Paints

Wire Nails

Corrugated Iron

Ridgings

"Pilot" Matches.

JOHN HOLT & Co. (L'pool)

BROAD STREET, LAGOS.

*Telegraphic Address* "EBANI"

# Lever Stores

## LIMITED,

WILL

## SHORTLY OPEN.

### LOOK OUT FOR

# Posters

GIVING DEFINITE DATE.

***A most wonderful assortment of all kinds of goods will be offered for sale up to ONE SHILLING.***

BUT

## Nothing in the Store over 1s.

# ILE IFI OJA AWON ENIA PAMO SI LAILEWU.

Nigbati Oja rẹ ba de lati Ilu Oyinbo, ti o si ni ẹ lara lati san owo Ibode lori won awa yio ba o gba Oja na, a o si ba o ṣe opo iwe gbigba won ni'bode.

Ti o ba si fẹ gba Oja rẹ na lọwọ wa, iwọ maṣe ṣopo ati gba gbogbo won le bikoṣe eyiti ipa rẹ ba kọkọ ka na lati sanwo 'bode fun.

Iwọ yio ri pe ọna yi na ẹ lẹhin ju pe ki o lọ t'ọrun bọ igbese lo!

Ẽra ko ni ra Oja rẹ na ti o wa ni itọju wa.

Abẹ abo Agbowo-ode Oba ni ile Ifi oja awon enia pamo si lodo wa wà

Igbakigba ti Oja rẹ ba tun de, ti owo ba si pọ lọwọ rẹ lati gba won, sa lọ ri Ọgbeni yi:—

**JAMESON,**

Ni Opopo-nla,

Leti Ile Dr. O. Sapara, I.S.O

l'Eko.

wonyi wo nibi

OROGBELE O! HARPER "ONINURE" LỌ!! GASA IGI MA DA O, HARRY ṢE BẸ O LỌ!!!

EYI DUN WA O!!!

Nitori kini, nitoripe Comp: of Customs ko ni ifẹ awọn enia dudu abẹ rẹ ni bi?

[*Lati ọwọ Samuel Woli Kekere.*]

Si Oni'we-irohin "Eko-Akete"

Baba ati Alagba nipa ore ọfẹ Ọlọrun maṣai jọwọ ki o gba mi laye ninu iwe rẹ lati sọrọ nipa Ọgbẹni Harry R. Harper "Oninure" Akọwe pataki, Akọwe kọ wura ọkunrin, Olori awọn Akọwe ni Ibode Ọba ni Iddo (*Customs Department Iddo*) lojiji li owurọ *Monday* to ṣe ọjọ 21 oṣu Jan. 1924 ni a gbọ iro pe Ọgbẹni "Oninure" yi ti palẹmọ o si ti wọ ọkọ *irin ajo* si aiye keji. A! ṣe mo ri Ọgbẹni na ni ọsan Satide 19/1/24 nigbati o ṣiwo lo si ile lati ibi iṣẹ? Nwọn ni bẹ ni, o tilẹ lọ si Ṣọṣi (*Church*) ọrọ ti ọjọ 20/1/24 'i alẹ ni o nmura lati lọ, bẹni "Oniwe iku" mu iwe rẹ de ti o si rọra na si, pẹlu itẹriba (bi ti ma mu tọ awọn ẹlomiran wa) ọna kọna ṣa ni ọna ti iku ngba wa pe ni, ọna jamba, ọna abosi, ona tara ati ọna wọrọkọ, ọna oke ati ti isalẹ, ọna ọtun ati osi, eyi keyi to wu ki o le jẹ, ọkan ṣa ni emi Samuel Woli Kekere mọ dajudaju "larin iye awa mbẹ ninu iku," "iṣisẹ kan ni mbẹ larin awa ati iku."

Eyi fi han ni pe a o sa ku dandan, lewe ati lọdọ, agba ati larugbo, "lilọ ni yio kẹhin *boy*" iku ni yio gbẹhin gbogbo awa ẹda ninu aiye, bo ti wu ki owo ati ilẹ rẹ ti pọ to, "erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ" ki iwe ori rẹ ki o ma ho ge bi iro okun, ki aiye rẹ ki o gun lati'bi de Kanu, ki ọgbọn ori rẹ ki o ju ti Solomon Ọba lọ, "erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ." Ki ọla ati agbara rẹ pẹlu ipo rẹ lode aiye ju ti Kiniwun lọ, ranti pe, "erupẹ sa ni iwọ, iwọ o si—:" ṣugbọn iwa ati iṣẹ olukuluku yio ma tọ lẹhin.

Gẹgẹ bi ati gbọ labari iku arakunrin wa "oninure" na si lẹhin ti awọn Oniṣegun bi mẹrin ti wadi rẹ kinikini, a gbọ pe nwọn ni (*heart failure*) ni tikiti (*ticket*) ti iku fi ranṣẹ si lati jẹ on kọ rẹ. Eyi ti wu ki o le jẹ nipa iku' Arakunrin wa yi, mo fẹ ki iwọ ọkawe mi yi mọ pe "iṣisẹ kan lo wa larin awa ati iku." Laisi aniani Ọgbẹni, Harry ti goke Jordani tirẹ.

Bi a ba ni ki a sọ nipa iwa Akọwe Agba "Oninure" yi emi Samuel Woli Kekere wi lai bẹru pe, ki ṣe Ọgbẹni yi ni iku "Omi gbigbona da mọ tutu" yi tọ si eyi keyi to wu ko le ṣe lẹkan si "erupẹ sa ni iwọ—:"

Niti iwa hihu ati ifẹ rẹ, ati ọrọ rẹ, ologbe yi ta wọn yọ, ni ti iwa olori bi ọga ni ibi iṣẹ rẹ loni awọn Akọwe rẹ ati Iranṣẹ rẹ, o ṣe iba tirẹ eyiti ẹnikan kan wọn ko le gbagbe lai, ni ibani-kẹgbẹ ati ifẹ ologbe, o fẹran enia to bẹ gẹ to nfi ọwọ kọ ălarù lọrun a si ma ba iranṣẹ (*Messenger*) rin pọ pẹlu, ọrọ sisọ rẹ, ikọ'we rẹ, ati ijoko lori aga ni ibi iṣẹ abi ni ibomira kọ ni ni ọgbọn pupọ. A ko gbọ ifisun ologbe yi lọdọ Oyinbo rẹ nipa awọn Akọwe rẹ lati igbati o ti de si Iddo. A! o maṣe o!! o di gbere ni yẹn Harry, o di arin nako, o doju ala ka to tun ri o Harper "Oninure." !!!

A ki Iya ologbe ati Iyawo pẹlu ọmọ ologbe ẹ ku irọju o, ki Oluwa ki o tu nyin ninu o, ki o si ṣe Baba, Ọkọ, Ọmọ fun nyin. A ki Ọgbẹni Manson Oyinbo o ku ọfọ airotẹlẹ ti Akọwe rẹ, a ki Ọgbẹni Leigh ti Ijọra ati awọn Akọwe rẹ, a ki Ọgbẹni Macaulay atẹle ologbe ni Iddo ati awọn Akọwe rẹ, ẹku ọfọ nla-nla yi o, ki Oluwa ki o yan Oninure bi ologbe fun nyin o, a ki nyin Ọgbẹni Bright Davies, Thomas Martins, Aṣọgbọn ati Willoughby ẹ ku ọfọ nla yi, ati ẹnyin Akọwe to ku, ẹ ku afẹku "Oninure" yi o.

O dun ni pupọ nigbati a ṣe akiyesi lati ri awọn Oyinbo ibi iṣẹ ologbe l'Eko ati ti Iddo ni ibi ikẹhin, ṣugbọn a ko ri ẹnikan, papa Ọgbẹni Manson ti ologbe jẹ Akọwe agba labẹ rẹ ni Iddo, A! bi Ọgbẹni Manson ti fẹran ologbe to yẹn!! Hap; nigba tọrọ Harper nigba sisi, eyi dun wa o, eyi si mu emi Woli Kekere bere "nitori kini" nitoripe Oyinbo Agba (*Comp. of Customs*) ko ni ifẹ awọn enia dudu abẹ rẹ ni bi? Mo tun bere laibẹru lọwọ Igbakeji rẹ (*Senior Colll. of Customs*) bi ologbe Harry R. Harper ko to (pẹlu gbogbo iṣẹ rẹ labẹ Asia Ọba wa lati ọdun gbọrọ yi wa) ẹniti o le yan Oyinbo kan lati ṣoju Oyinbo Agba lati fi ifẹ ati iyi iṣẹ ologbe yi han? A ko sa mo; olukuluku lo sa ni agbelebu rẹ to ngbe kiri.

"O san lati ma lọ si ibi ọfọ ju ibi Iyawo lọ," nitori eyi ni igbẹhin olukuluku."

"Ke rara ma si ṣe dasi, gbe ohun rẹ soke bi ipẹ, ki o si fi irekọja awọn enia mi han wọn, emi ni iranṣẹ ife ati Ile Jakobu ẹṣẹ wọn. *Isiah 58. 1.*

SAMUEL—*Woli Kekere.*

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay,**
88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orișirisi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orișirisi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orișirisi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

# A. KESSLER,

7, Labinjọ Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER.

The German Trading House, Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine, as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Descent Wristlet Watches sh. 8/- and sh. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite

CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.

# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

**Prices to suit everybody.**

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile lọ ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olowọ—agaga, Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *lọnu* a le ta a fun o. Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Oriṣiriṣi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja iro wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan, 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kowe ṣowo yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBẸ & BROS,
38, Moloney bridge Street, Lagos
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis*),
Idumagbo, Eko.

## KNOW ALL MEN

That I, formerly known as

ISAAC AKINỌLA COLE

Builder & Contractor of No. 1, Market Street and 48, Breadfruit Street, Lagos Nigeria, desire to be known, called and addressed from the first day of January 1924 as

ISAAC AKINỌLA OGUNMỌDẸDE

All Transaction, Documents, Papers etc., bearing the first name remain valid.

Dated at Lagos this 24th day of December, 1923.

I. A. COLE

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION

TO

S. I. M. Johnson,

9, Scale Square,

Phone 227 Lagos,

P.O. Box 498.

**Chairs! Chairs!! Chairs!!!**

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,

J. A. OSHODI,

26, OBUN-EKO STREET,

LAGOS.

**AGA, AGA, AGA.**

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO POKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½D.) KOBỌ KAN PẸLU ABO.

Lo si ọdọ ALABOJUTO,

Ọgbẹni J. A. OSHODI,

No. 26, ITA OBUN-EKO,

LI EKO.

**The Kaduna Store,**

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

EBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to buy always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz :—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE : CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS :—Cash with Orders.

ILE OWO KADUNA,

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Tho.

75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamo) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 lati wa lẹnu işẹ yi, awọn ọja wa si to ọja o ni igba poun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi ti pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma gbe'ro : a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹro-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun şe ti a si tun nta lowo pọ, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ẹniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe sọwọ si Olotu Ile-owo yi :—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta daruko loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

ORIRE N'TAWO.

Domingo Olorire, Alọgbọn-agba-ni'kun (*Native Doctor*) tun gbe işẹ rẹ sode fun ẹnikẹni ti o ba nfẹ.

☞ "Mori lọ ma mẹwa lọ" si Ile Orire, 23, Kano Street, Ebute Mẹta, ti a nşi silẹ ni agogo mẹwa owurọ titi di agogo mẹla alẹ lojojumọ, afi ọjọ ọsẹ.